Bibeli fun awon omode

# Josua gba isakoso



Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Janie Forest
Alastair Paterson

Olu'lo: Ruth Klassen

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Mose ku, Josua mo pe Olorun ti yan oun bayii lati dari awon omo Isreali.  Siwaju ki Josua to se ipalemo omo ogun re, O ti pese ara re.  Olorun se ileri isegun ati asiri fun Josua ni ile ileri naa bi awon eniyan ba le maa pa oro Olorun mo.





Awon omo Isreali se ileri lati tele Josua ati pe nigbagbo ni awon o maa pa oro Olorun mo pelu ogbon, adari tuntun naa ran ami to si Kenaani lati lo wo idabobo ti ilu nla ti Jeriko. Nibe ni won ti jagun Isreali akoko.



Enikan so fun oba ti Jeriko pe awon ami wa ni ilu. O ran omo ogun re lati lo wa won. Wiwa won bere lati ile Rahabu, nibiti awon okunrin naa duro si. Awon omo ogun n pooyi lenu ilekun re. Ni Kankan Rahabu fi awon okunrin naa pamo soke aja ile.

Nigba ti awon omo ogun lo, Rahabu fi okun so awon okunrin naa kale ni alaafia si eyin odi ilu. Kin ni o de ti o fi ran awon ami yii lowo? Nitori pe o mo pe Olorun wa pelu won. On fe ki Olorun da emi oun si. Awon ami se ileri lati da Rahabu ati ebi re si.



Ki won to de Jeriko, awon omo Isreali ti koja odo Jordani siKenaani, ile ileri.  Sugbon ko si afara! Bawo ni awon eniyan naa yoo se koja.



Olorun so fun Josua, alufaa pe dari awon omo ogun ati eniyan ki won gbe apoti ti o ni ofin mewaa ninu. Nigba ti ese alufaa ba kan egbe omi, Olorun yoo se iyanu.  Olorun mu ki ile gbigbe wa laarin omi.



Leyin ti gbogbo awon eniyan ti koja ni alaafia, Won gbe Okuta nla mejila ninu odo bi ibusun ati mejila miran leti inu odo Kenaani. Iwonyi je iranti lati ran awon eniyan ti o ko awon omo won nipa agbara nla Olorun ati ife.





Jeriko ni
agbara, O si ni
ogiri ti o nipon
Bi Josua se n
seto ikolu re,
Olorun ran awon
adari omo ogun
re lati orun o si
ran adari Isreali
tuntun leti pe
Olorun bori
ogun fun awon
eniyan re.



Olorun so fun Josua bi yoo se kolu Jeriko.  O je eto ti o se ajeji.  Awon eniyan Olorun ni lati yan yipo ilu naa ni eekan lojumo fun ojo mefa ati leemeje ni ojo keje.  Nigba naa won yoo fon fere ati ariwo, odi ilu naa yoo si wo lulo.

Josua ati awon omo ogun re se bi Olorun ti pase fun won.  Boya awon eniyan ni Jeriko yoo fi won rerin-in, sugbon leyin yiyan ikeje ni ojo keje alufaa fon ohun ipe, gege bi Olorun ti se ileri... odi nla ti Jeriko wo lule.










Ile Rehabu nikan ni o gbala ninu odi naa, O fi okun ti, o fi ko lara ferese sile kiakia, awon eniyan josua gba Rahabu ati ebi re la. Nigba naa ni Jeriko di ibaje gege bi ase Olorun.



Joshua yonda wura jeriko, fadaka ati ohun eso fun Isin Olorun... O fi enikeni ti o ba tun ilu buburu naa ko geegun-un. Laipe gbogbo eniyan ni Kenaani gbo bi Joshua se segun / bori Jeriko.

Josua gba isakoso

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Joshua ori kin-in-ni titi de ori kefa

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe:
Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.